# Ofin ati Awọn ilana fun Iṣẹ amurele – Ile-ẹkọ Jẹleosinmi titi de Giredi 12

## Ofin ati Awọn ilana Iṣẹ amurele Titun

Ni Oṣu kọkanla ọdun 2008, Ajọ Ile-iwe Ijọ Aguda (Katoliki) ti Agbegbe Dufferin-Peel yan lati mu ofin ati awọn ilana fun iṣẹ amurele titun kan lo fun Ile-ẹkọ Jẹleosinmi titi de Giredi 12, eyi ti a o mu wa si imulo ni Oṣu kẹsan ọdun 2009. Awọn ofin ati ilana naa nfi oju iṣe awon Ijọ Aguda (Katoliki) wo iṣẹ amurele, eyiti o mọ bi akoko idile ti ṣe pataki to, ti o si nbu ọla fun asopọ ti o wa laarin ile-iwe, idile ati ijọ agbegbe. Gẹgẹ bii awujọ, a wa mọ wipe bi awọn asopọ yi ba ṣe lagbara si ni awọn akẹkọ wa yoo ṣe le kọ ẹkọ daradara si, ti wọn yoo si le mu awọn akanṣe talẹnti ati awọn ẹbun ti a fi bukun wọn dagba si.

## Itumọ Iṣẹ amurele

Awọn ofin ati ilana naa tumọ iṣẹ amurele gẹgẹ bii *iriri ikẹkọ ti olukọ pin fun ni, eyiti a gbọdọ pari ni akoko ti o yatọ si ti yara ikawe, eyiti o si nṣe atilẹyin fun kikọ ẹkọ ati didagbasoke akẹkọ kọọkan, ti o si nmu ẹkọ-kikọ ati idagbasoke wọn gbooro sii.*

## Awọn ohun ti a fi nda Iṣẹ amurele ti o Munadoko mọ

Awọn ofin ati ilana ko nilo wipe ki a pin iṣẹ kan lojoojumọ. Nigbati a ba pin iṣẹ amurele ẹ̀wẹ̀, eyi gbọdọ ni nkan ṣe taara pẹlu nkan ti akẹkọ nkọ ni yara ikawe, ki o si ni awọn aami wọnyi:

- o ni itumọ, o si wulo;
- a ṣe eto rẹ pẹlu erongba ati yẹra fun didi iṣẹ ti o pọju ru akẹkọ;
- o jẹ ohun ti olukọ naa ṣe alaye rẹ ni yekeyeke, o si ye awọn akẹkọ;
- o jẹ ohun ti a ya sọtọ, gẹgẹ bi eyiti o tọ lati koju kikọ ẹkọ akẹkọ;
- o jẹ ohun ti a ti nṣe ayewo rẹ ni akoko ti o yẹ.

Iṣẹ amurele ko dale awọn iṣẹ ti a fi pẹnsulu ati iwe nikan ṣe. O le ni awọn iṣẹ miiran ninu bii mimurasilẹ, ṣiṣe ayẹwo, gbigbaradi, fifi ọrọ wanilẹnuwo, ṣiṣe iwadi ati kikọ ẹkọ fun apẹẹrẹ.

## Awọn orisirisi Iṣẹ amurele Ti a ma nsaba Pin

Tabili ti o wa ni isalẹ yi jẹ eyiti a gbe kalẹ labẹ ofin ati ilana iṣẹ amurele Dufferin-Peel. O ṣe apejuwe oriṣi iṣẹ amurele mẹrin ti a ma nsaba pin, ati awọn abajade ti a ni lọkan.

| ORIṢI | ITUMỌ | ABAJADE TI A NI LỌKAN |
|---|---|---|
| Iṣẹ amurele Fun Pipari | Eyikeyi iṣẹ ti a pin fun akẹkọ latari awọn itọnisọna ti a bẹrẹ ninu yara ikawe, ti a si pari ni ile | Nran awọn akẹkọ lọwọ lati doju oṣuwọn awọn eto itọnisọna |
| Iṣẹ amurele fun Igbaradi | Eyikeyi iṣẹ ti o nṣe ayẹwo, ti o si nmu awọn iṣẹ ọpọlọ ati ero ti a ti kọ ni yara ikawe lagbara sii | Nran awọn akẹkọ lọwọ lati mu ki awọn iṣẹ ọpọlọ ti wọn ṣẹṣẹ kọ gbooro sii, ati ki wọn si le mu awọn ero titun tẹsiwaju |
| Iṣẹ amurele fun Imurasilẹ | Eyikeyi iṣẹ ti o ba npese awọn akẹkọ silẹ fun ẹkọ titun tabi ayẹwo ni soki fun ohun ti nbọ wa | Eyi nfẹ ki awọn akẹkọ ko alaye tabi awọn ohun ti o nii ṣe pẹlu aṣa tabi itan jọ, ni imurasilẹ fun kiko ẹkọ, tabi o nfẹ ki awọn akẹkọ murasilẹ fun idanwo, fifi imọ ẹni han, fifi isẹ ẹni han, ati bẹẹ bẹ lọ |
| Afikun AkokoAwọn isẹ akanṣe/Awọn isẹ amurele Pataki | Eyikeyi iṣe ti nṣe awari ikọni ni ọna ti o yatọ tabi ti ti o nṣe asopọ/nmu kikọ ẹkọ ninu yara ikawe gberu | Ngba awọn akẹkọ ni imọran lati tan iṣoro, ronu ni ọna lati ṣẹda ohun titun ati lati ronu daradara |

*“Fun olododo ni imoran, imo won yoo si po sii”* – Iwe Owe 9:9

Awọn ilana ni pato

Tabili ti o ni isalẹ yi wa jẹ eyiti a gbe kalẹ labẹ ofin ati ilana iṣẹ amurele Dufferin-Peel. Eyi ntọkasi awọn ero ni pato fun ipin kọọkan ti o nii ṣe pẹlu orişi iṣẹ amurele ati bi wọn ti ṣe pọ to.

| | |
|---|---|
| **Kindergarten:** *Iwadi nfihan wipe asopọ ti o lagbara wa laarin ilọwọsi idile ati aṣeyori akẹkọ.* | |
| Kikọ ẹkọ ni ita yara ikawe ni Ile-ẹkọ Jẹleosinmi gbọdọ ni ere ṣişe, ọrọ sisọ, fifi eti silẹ, wiwo nkan ati kika iwe ni ede Gẹẹsi tabi ni ede abinibi idile ninu. *Olukọ naa le pese awọn aba ati ohun elo fun awọn iṣẹ kikọ ẹkọ ti o jẹ aṣayan, ni ita yara ikawe (fun apẹẹrẹ Iwe akamọra, ati bẹẹ bẹ lọ). Awọn aba siwaju sii wa ni http://www.gov.on.ca/children. | A ko **gbọdọ*** pin iṣẹ amurele fun awọn akẹkọ ti o wa ni ile-ẹkọ jẹleosinmi. |
| **Ile-iwe alakọbẹrẹ (Awọn giredi 1-3):** *Iwadi nfihan wipe asopọ ti o lagbara wa laarin aṣeyori akẹkọ ati kika iwe fun/pẹlu awọn akẹkọ ti o wa ni ile-iwe alakọbẹrẹ, lojoojumọ, ni ede Gẹẹsi tabi ni ede abinibi.* | |
| Iṣẹ amurele ni awọn giredi alakọbẹrẹ yoo ma waye gẹgẹ bii iwe-kika, ere-ṣişe, ifọrọwerọ, ifetisilẹ, wiwo nkan ati awọn iṣẹ ti o nii ṣe pẹlu ajọṣepọ, bii ile-kikọ ati ina dida pẹlu idile. Awọn aba siwaju sii wa ni http://www.gov.on.ca/children. Ni awọn giredi alakọbẹrẹ ti o ti tẹsiwaju, iṣẹ amurele le bẹrẹ si jẹ iru iṣẹ adanikanṣe. | Iṣẹ amurele ojoojumọ ki yoo kọja, ni apapọ, **ogun (20) iṣẹju**. |
| **Junior (Awọn giredi 4-6):** *Iwadi nfihan wipe iṣẹ amurele npese awọn anfaani fun awọn akẹkọ ti o wa ni giredi junior, papa julọ, ni ọna ti o nii ṣe pẹlu ihuwasi akẹkọ si ile-iwe ati si ẹkọ-kikọ.* | |
| Iṣẹ amurele ni awọn giredi junior le jẹ iru iṣẹ ti wọn yoo danikan ṣe. | Iṣẹ amurele ojoojumọ ki yoo kọja, ni apapọ, **ogoji (40) iseju**. |
| **Intermediate (Awọn giredi 7 & 8):** *Iwadi nfihan wipe iṣẹ amurele le ko ipa lati mu aṣeyori awọn akẹkọ intermediate gberu.* | |
| A o ṣeto iṣẹ amurele ni ọna ti ki yoo fi di iṣe ti o pọju ru akẹkọ. | Iṣẹ amurele ojoojumọ ki yoo kọja, ni apapọ, **ọgọta (60) iṣẹju**. |
| **Secondary Intermediate (Awọn giredi 9 & 10):** *Bi o ti le jẹ wipe iwadi nfihan wipe awọn anfaani ti o nii ṣe pẹlu iṣẹ amurele ga ju ni awọn giredi sekọndiri, ẹri tun fihan wipe idaamu ti o nii ṣe pẹlu iṣẹ amurele wọpọ laarin awọn akẹkọ ti o wa ni ẹgbẹ yi.* | |
| A o ṣeto iṣẹ amurele ni ọna ti ki yoo fi di iṣe ti o pọju ru akẹkọ. | Isẹ amurele ki yoo kọja **ogun (20) iṣẹju** ni ọjọ kan fun iṣẹ kan. |
| **Secondary Senior (Grades 11&12):** *Bi o ti le jẹ wipe iwadi nfihan wipe awọn anfaani ti o nii ṣe pẹlu iṣẹ amurele ga ju ni awọn giredi sek¬ondiri, ẹri tun fihan wipe idaamu ti o nii ṣe pẹlu iṣẹ amurele wọpọ laarin awọn akẹkọ ti o wa ni egbe yi..* | |
| A o ṣeto iṣẹ amurele ni ọna ti ki yoo fi di iṣe ti o pọju ru akẹkọ. | Iṣẹ amurele ki yoo kọja **ọgbọn (30) iseju** ni ọjọ kan fun iṣẹ kan. |

### Ṣişe atilẹyin fun Ọmọ Rẹ pẹlu Iṣẹ amurele

Awọn itanilologo wọnyi le ran awọn idile lọwọ nipa ṣişe atilẹyin fun ọmọ wọn pẹlu iṣẹ amurele:

1. Ṣeto akoko kan ni pato lẹyin ile-iwe fun ọmọ rẹ lati ṣe iṣẹ amurele.
2. Wa nibẹ lati pese iranlọwọ fun ọmọ rẹ lai ba a ṣe iṣẹ naa.
3. Fi inu didun rẹ han si kikọ ẹkọ ọmọ rẹ nipa biba a sọrọ nipa ọjọ rẹ ni ile-iwe.
4. Ka orişirişi iwe fun ọmọ rẹ, ati pẹlu rẹ.
5. Fi mimọọkọ-mọọka ati mimọ nipa işiro ninu awọn iṣẹ ojoojumọ rẹ han, fun apẹẹrẹ, nipa kika iwe-iroyin, kikọ akojọ awọn ewebẹ ati eso ti a fẹ ra l'ọja, wiwọn nkan, tabi ṣişe işiro iye ti nkan jẹ.
6. Pese awọn iṣẹ ti a nfi ọwọ ṣe fun awọn ọmọde, bii pipese ounjẹ, ṣişe iṣẹ ọnà ati iṣẹ ọwọ, ati ṣişe ere oni lẹta ati ọrọ.
7. Din wiwo ẹrọ amohunmaworan ati "akoko imọ ijinlẹ" miiran ku, papa bi ọmọ rẹ ba nni işoro nipa pipari iṣẹ ile-iwe.
8. Kan si olukọ ọmọ rẹ bi o ba ni aibalẹ ọkan nipa iṣẹ amurele ọmọ rẹ.

### Afikun Atilẹyin

www.dpcdsb.org/homework npese ẹda awọn ilana iṣẹ amurele kan lori ayelujara ati awọn ohun ti nṣe atilẹyin

http://www.mississauga.ca/portal/residents/homeworklinks npese awọn ohun ti nṣe atilẹyin fun iṣẹ amurele kan lori ayelujara

www.caledon.library.on.ca npese awọn ohun ti nṣe atilẹyin fun iṣẹ amurele kan lori ayelujara

www.orangeville.library.on.ca npese awọn ohun ti nṣe atilẹyin fun iṣẹ amurele kan lori ayelujara

www.ilc.org npese iranlọwọ iṣẹ amurele lori ayelujara bi o ṣe nlọ lọwọ, lati ọdọ olukọ ti o k'ọṣẹ gba iwe-ẹri